# Ọjọ Naa Ni Kalfári

Jeffersonville, Indiana, USA

Ọjọ Karundinlọgbọn, Oṣu Kẹsan,1960

1 Ki Ọlọrun ko bukun fun ọ, Arakunrin Neville. Mo dupẹ, pupọ. Ẹ kaarọ ẹyin ọ̀rẹ́. O jẹ anfani lati tun wa ni agọ-ijọsin lẹẹkan si ni owurọ yi lati le sin Oluwa nipasẹ wiwaasu Ọrọ naa ki ń si gbadura fun awọn alaisan. Mo si dupẹ pupọ fún ọjọ oni.

O yà mi lẹnu ni gẹ́lẹ́ ti mo wọlé. Arakunrin kan rin wá o si sọ wipe, "Emi ko ni dabi adẹ́tẹ̀ aláìyẹ ti a mu larada." O jẹ Arakunrin Wright. Mo gbadura fun un, Ọlọrun si wò o san patapata. O gòkè wá o ń sọkun nigbati o fẹ bọmi lọwọ, o si sọ wipe oun fẹ́ dúpẹ́ lọwọ Oluwa fun imularada. O fẹ padawa ki o si wa dúpẹ. Gbogbo rẹ̀ ti lọ. O ti ni ilera pipe bayi. A dupẹ fun awọn ẹrí wọnyí.

2 Charlie, ìwọ ati Arakunrin Jefferies, ti ẹ ba nifẹ si i, ẹ goke wa siyin ki ẹ si wa mu ijoko yin nibiyi. A fi tọkantọkan ki yin kaabọ ẹ kò nilo lati wa ni idúró. Arakunrin miran ti o wá ni ibẹyẹn, Arakunrin Woods, kan goke wá nibiyi, awọn àyè wà nibiyi lori àga-gígùn nitorina ẹ ko nílò lati dide duro. Mo gbagbọ pe awọn àyè wà nibiyi. A fi tọkantọkan ki yin kaabọ bi ẹ tị se ń bọwa lati joko nibi awọn àyè wọnyi.

Inu wa dùn .... Mo gbagbọ pe a sọ bayi nigbakan pé "Inú mi dùn nigbati wọn sọ fún mi pe, ẹ jẹ ki a lọ si ile-Oluwa." Eleyi jẹ́ anfani ati ayọ onigbagbọ - lati lọ si ìlé Oluwa.

3 Nigbati mo wo yika mo ri ọpọlọpọ awọn ọ̀rẹ́ mi ni owurọ yí, inú mi dùn jọjọ nipa èyí. Inu mi dùn lati ri Arakunrin ati Arabinrin Dauch nibiyi lati ilu Ohio. Mo ri Arakunrin ati Arabinrin Armstrong lẹhin lọhun lati ibiti o jinna, ilu Ohio. Ki Ọlọrun kó bukun fun gbogbo yin patapata pẹ̀lú. Ati oo, ti mo bá kàn wò yíká iwọ yoo ri ọpọlọpọ o nira lati le ranti orukọ gbogbo wọn. Arabinrin Hoover, inu wa dùn lati ri ọ ni owurọ yi lati ilu Kentucky. Ati Charlie ati Nellie, Arakunrin Jefferies ati ebí rẹ̀, ọpọlọpọ ni o si wá lati ita ilu. Nitorina a ń reti akoko ti o lagbara ninu Oluwa ni owurọ yi. A n reti pe ki Ọlọrun ko ba wa pàdé ni ọ̀nà ti yoo fi bukun fún ọkàn wa ki o si ba gbogbo aini wa pàdé, awọn ohun ti a nilo. Gẹgẹ bi mo ti wò yika gbọngan yi, ti o ba jẹ wipe emi yoo maa pe gbogbo orukọ awọn ọrẹ mi ti o wa nibiyi, emi yoo gba gbogbo owurọ lati ma a pe oriṣiriṣi wọn. O jẹ ki n ni imọlara ti o dára pe mo pada wa sinu ile-ijọsin ki n si ri gbogbo awọn eniyan wọnyi ninu ile ijọsin.

4 Bawo ni yoo ṣe ri nigbati a ba de ọrun, ti a o si pade nibẹ fun akoko ayeraye, idapọ ailopin papọ ni ayika ìtẹ́ Ọlọrun - ati ibukun naa ti gbogbo wa bu ọlá fun? Nibẹ ni a ti ri bi aworan Rẹ gẹgẹ bi ìrísì Rẹ, ati Ẹmi Rẹ lori wa lati jọsin ati lati sin I fun ayeraye, nibiti a ko ti ni dagba pẹlu ikaarẹ.

Kan ronú, ko si ohunkohun ti o le ronu nipa rẹ, eyiti o nifẹ lati maa ṣe, ṣugbọn lẹẹkọọkan o maa n kàárẹ́ lati ṣe e. Charlie, mo ro wipe iwọ ati emi ti ṣọdẹ ọkẹrẹ ni ọpọlọpọ igba ju ohun miran ti a nifẹ lati ṣe lọ ni ọna yi. Ṣugbọn ṣe ẹ mọ̀ nigbamiran aarẹ maa mu ọ lati ṣe e. Mo nifẹ lati maa rin ọpọlọpọ ibusọ pẹ́lú ẹsẹ̀, maa lọ si ibi awọn oke, emi yoo si rin lọ si ibẹ, ṣugbọn nigba miran aarẹ yoo mu ọ nipa rẹ, iwọ yoo si fẹ ṣe ohun miran. Mo fẹran lati wa ọkọ̀.

Nigba miran mo maa n ni imọlara pe aarẹ mu mi, ko si okun ninu mi mọ mo si ni aibalẹ ara. Emi yoo wọ inu ọkọ ayọkẹlẹ mi emi yoo si jade lọ. Emi yoo mu ọ̀pá-iwakọ̀ n o si wakọ lọ si isalẹ oju-popo n o si maa kọrin pe "inu mi dun pe mo jẹ ọkan ninu wọn" tabi ohun kan. Emi yoo di ọ̀pá-íwakọ naa mú n o si maa kọrin n o fi ẹ̀sẹ̀ mi lùlù n o si maa pariwo. O dara, lẹhin igba diẹ yoo rẹ̀ mi, ati lẹhin naa emi yoo pada si ilé n o sị se ohun miran. Ṣugbọn nigbati a ba n jọsin fun Ọlọrun ni ilu tuntun naa, kò ni si akoko ikaarẹ kankan. Yoo jẹ ibukun nigba gbogbo yoo si maa tẹsiwaju si. Ṣugbọn ni dajudaju a o ti yi wa pada nigba naa, a ko ni ri bi a ti se ri nisisiyi. A o ti yatọ, a o ti di ẹ̀dá ti o yatọ ju bi a ti ṣe ri nisisiyi lọ. Nitorina inu wa dùn.

5 Emi kan n ronu. Emi ko mọ boya mo ti sọ eleyi ri tabi n ko ti sọ ọ, Arakunrin Charlie. Nigba kan mo wa pẹlu rẹ ni ilu Kentucky, o si sọ wipe, "Arakunrin Branham, ṣe o ro pe ni ijọba ẹgbẹrun ọdún iwọ ati emi yo ṣọdẹ ọkẹrẹ?"

Mo wipe, "Emi kò ro bẹ, Charlie."

O wipe, "O dara, a fẹran rẹ pupọpupọ, ṣe o ro pe a o ṣe bẹẹ ni ijọba Ẹgbẹrun ọdun?"

Mo wipe, "Rara, a ko ni pa ohunkohun ni ijọba Ẹgbẹrun Ọdun."

O si wipe, "O dara, a o kan nifẹ rẹ̀."

Mo wipe, "Charlie, kini ti n ba le ṣalaye fun ọ ti mo si yi ọ lọkan pada pe ni igba kan o jẹ ẹlẹdẹ, a si gbe ọ ga soke si ẹ̀dá ti o ga julọ, si ẹ̀dá kan ẹ̀dá eniyan. Ṣe iwọ yoo nifẹ lati pada lọ ki o si maa gbadun gbogbo iwa ẹlẹdẹ?"

O wipe, "Rara."

Mo wipe, “Ṣe o ri, iwọ ti ga ju ẹlẹdẹ lọ nisisiyi iwọ ti di eniyan, iwọ ko ni fẹ pada di ẹlẹdẹ mọ́.” Mo wipe, “Nisisiyi, ṣe iṣiro eyi lọna ẹgbẹrun mẹwa, ohun ti iwọ yoo jẹ niyi nigbati a ba yi ọ pada kuro nibiyi si ohun ti iwọ ṣi maa jẹ́. Iwọ ko ni fẹran lati pada si eniyan ẹlẹran ara mọ.” Eyi jẹ otitọ̀. Yoo jẹ ohun ti o yatọ. Ironu rẹ lasan jẹ ki inu mi ki o dùn, ti mo mọ pe ni ọjọ kan a o goke lọ.

6 O dara, nisisiyi ti Oluwa ba fẹ ni ọjọ isinmi ti o ń bọ̀, eyiti yoo jẹ bi i .... Lẹhin naa emi yoo kuro nibiyi lati lọ si ilu Wyoming pẹlu ọrẹ daradara mi kan, Arakunrin Minor Arganbright, ati Arakunrin Clayton Sonmore, ti ẹgbẹ awọn ọkunrin oniṣowo Kristẹni.

Ni ọsẹ to n bọ .... ọsẹ to tẹle ọsẹ to n bọ ohun ni .... o jẹ ekeje bayi. Emi yoo wa ni ilu Dallas, Texas, ni Agọ-Ajọ ohun Iwosan, emi yoo si sọrọ ni aṣalẹ ni ọjọ keje. Ati lẹhin naa emi yoo pada wa lati lọ si ilu Idaho pẹlu Arakunrin Arganbright ati awọn ọkunrin oniṣowo Kristẹni, ati boya a o ni alẹ ọjọ kan ni ilu Minneapolis ki a to kuro nibẹ. Lẹhin naa a o ni ounjẹ àárọ̀ ẹyọkan ti ẹgbẹ awọn ọkunrin oniṣowo Kristẹni.

Ti Oluwa ba fẹ ni owurọ ọjọ isinmi ti o n bọ mo fẹ pada sibiyi ni agọ ijọsin yi lẹẹkan si. Ti a ba si fi àyè gba eleyi, ti o ba si jẹ ifẹ Oluwa, mo fẹ sọrọ lori akori kan ti a pe ni “Iji Naa Ninu Afẹfẹ” - Ti Oluwa ba fẹ́.

7 Eleyi ti wa ninu ọkan mi ni gbogbo ọ̀sẹ̀.

Ati ni owurọ ọjọ kan, ni kùtùkùtù owurọ ni bi i agogo mẹrin owurọ, mo ji dide mo si ronu nipa èyí. “Ọjọ Naa Ni Kalfari.” Mo si fẹ sọrọ lori eleyi ni owurọ yi. Ọjọ Naa Ni Kalfari.

Bayi fun kika ẹ jẹ ki a ṣi Bibeli wa, ninu Iwe Mimọ, si Iwe Ihinrere ti Matiu Mimọ ni ori kẹta-din-lọgbọn, a o si bẹrẹ pẹlu ẹsẹ kẹta-din-lọgbọn a o si kà lati ara Iwe-Mimọ yi ki a le ni ipilẹ wa. Lẹhin naa a o bẹrẹ ni kètè, ati lẹhin isin iwaasu lẹhin naa a o gbadura fun awọn alaisan.

8 Lati akoko ti o gbẹyin nibiyi, mo ṣẹṣẹ fẹ pada mu ilana iṣe-iranṣẹ mi tuntun wa, mo ni ọpọlọpọ ẹ̀rí ti a sọ lẹhin ipade yi ju gbogbo awọn ẹri ti a ti sọ lati inu awọn ipade miran fun igba pipẹ. Ohun kan wa nipa eyi, o gbọdọ ni ọna lati tún ba eniyan naa sọrọ, laibikita bi a tị se fi ọwọ-agbara nla han to. Ṣugbọn ṣe ẹ ri, iwosan duro lori igbagbọ ẹnikọọkan.

Nisisiyi, ti aladori ẹnikọọkan ba ni igbagbọ, ti wọn si ri bi Ẹmi Mimọ tị se lọ sori awọn eniyan ninu apejọpọ ti o si sọ ohun kan pàtó, ti ohun kan gbòògì si ṣẹlẹ (“O jẹ́ irú ẹni bayi ati orukọ rẹ niyi, o si wá lati iru ibi bayi, ati iru nkan ti o tị se, yoo si ri bi eleyi”) ti ẹ si ri ti gbogbo rẹ ṣẹlẹ gẹlẹ ni ọna yi, sibẹ ẹnikọọkan ti o joko nibẹ gbọdọ gboju soke ki o si sọ wipe, “Eleyi gbọdọ jẹ Ọlọrun! Mo tẹwọ gba iwosan mi.” Ṣugbọn dipo eleyi aladori ẹnikọọkan sọ wipe, “Gbe ọwọ le mi ki o si gbadura fun mi ki ara mi si yá.”

9 Ṣugbọn bayi ni a tị se kọ́ wa ni ilu Amẹrika nibiyi lati gba eyi gbọ, eyi si ba Bibeli mu, dajudaju. Ṣugbọn nisisiyi a ri ni orilẹ-ede Afrika ati oriṣiriṣi ibi gbogbo, saa jẹ ki iru nkan bayi ṣẹlẹ, gbogbo apejọpọ ni yoo gbe ọkan wọn soke ni ẹẹkan wọn yoo si ri iwosan wọn gbà - nitoripe wọn ko ti kọ wọn ni ohun kankan. Ṣe ẹ ri, wọn ko ti kọ wọn ni iwosan. Ati nigbati wọn ba ri eyi, wọn yoo mọ pe Ọlọrun kan wa tị o wà laaye ti O ba si wà laaye, O jẹ Ọga-ogo julọ, O si n ṣe iwosan, ohun si niyi. Nitoripe a ti fi ipilẹ naa lélẹ̀-ipilẹ naa - pé Oun ni Oluwosan O si maa n wo awọn eniyan sàn. Lẹhinaa nigbati wọn ba ri ifarahan Rẹ ti O n sisẹ nipasẹ Ijọ Rẹ, lẹhinnaa, wọn yoo sọ wipe, “Eyi ti to fún wa. Gbogbo ohun ti a nilo niyi.” Ṣugbọn a ti kọ wa nipa gbigbe ọwọ́ le alaisan ati irú nkan bayi. Idi niyi ti ko fi n ṣiṣẹ daradara ni orilẹ-ede Amẹrika.

Bayi, ranti, ni owurọ ọjọ isinmi ti o n bọ, ti Oluwa ba fẹ́ (Arakunrin Neville yoo ṣe ìfilọ̀ rẹ̀, ni dajudaju), “Iji Kan Ninu Afẹfẹ Naa.”

10 Bayi, mo n fun yin ni akoko diẹ lati le ṣi Iwe Mimọ si Iwe Matiu ori kẹta-din-lọgbọn. Ẹ jẹ ki a bẹrẹ si ni kà lati ẹsẹ̀ kẹta-din-lọgbọn ti Iwe Ihinrere ti Matiu. Nisisiyi ẹ jẹ ki a tẹti silẹ daradara si kika Ọrọ.

*Nigbana li awọn ọmọ-ogun Baalẹ mu Jesu lọ sinu gbọngan idajọ, nwọn si ko gbogbo ẹgbẹ́ ọmọ-ogun ti i*

*Nwọn si bọ aṣọ rẹ̀, nwọn si wọ ọ li aṣọ ododo.*

*Nwọn si hun ade, ẹ̀gún, nwọn si fi de e li ori, nwọn si fi ọ̀pá iye le e .... li ọwọ ọ̀tún: nwọn si kunlẹ niwaju rẹ, nwọn si fi i ṣẹsin, wipe, kabiyesi, ọba awọn Ju.*

*Nwọn si tutọ si i lara, nwọn si gba ọ̀pá ìyè naa, nwọn si fi lu u li ori*

*Nigbati nwọn fi I ṣ̀ẹsín tan, nwọn bọ aṣọ na kuro lara rẹ, nwọn si fi aṣọ rẹ wọ ọ, nwọn si fa a lọ lati kan a mọ agbelebu.*

*Bi nwọn si ti jade, nwọn ri ọkunrin kan ara Kirene, ti njẹ Simoni: On ni nwọn fi agbara mu lati*

*ru agbelebu rẹ.*

*Nigbati nwọn si de ibi ti a n pe ni Golgota, eyini ni, ibi agbari,*

*Nwọn fi ọti kikan ti a dapọ mọ òróró fun u lati mu: .... nigbati o si tọ ọ wo, o kọ lati mu u.*

*Nigbati nwọn si kan a mọ agbelebu, nwọn pin aṣọ rẹ, nwọn si ṣé gẹ̀gẹ́ lee: ki eyi ti wolii wi ba le sẹ, pe Nwọn pin aṣọ mi fun ara wọn aṣọ ileke mi ni nwọn ṣẹ gègé le.*

*.... Nwọn si joko, nwọn nṣọ ọ nibẹ.*

*Nwọn si .... ti ọran ifisùn rẹ ti a kọ si ìgbèrí rẹ̀, EYI NI JESU ỌBA AWỌN JU.*

*Nigbana li a kan awọn ole meji mọ agbelebu pẹlu rẹ̀, ọkan li ọwọ ọtun, ati ekeji li ọwọ òsì.*

*Awọn ti nkọja lọ si n fi ṣe ẹlẹya, nwọn si n mi ori wọn.*

*Wipe, iwọ ti o wó tẹmpili ti o si kọ ọ ni ijọ mẹta, gba ara rẹ là. Bi iwọ bạ se Ọmọ Ọlọrun, sọkalẹ lati ori agbelebu wá.*

*Gẹgẹ bẹẹ li awọn olori alufa pẹlu awọn akọwe ati awọn àgbàágba nfi ṣe ẹlẹya, wipe,*

O gba awọn ẹlomiran là, ara rẹ ni ko le gbala. Ọba Israẹli sa ni iṣe, jẹ ki o sọkalẹ lati ori agbelebu wá nisisiyi, awa o si gba a gbọ́.

*O gbẹkẹle Ọlọrun, jẹ ki o gba a la nisisiyi, bi o ba fẹran rẹ́: O sa wipe. Ọmọ Ọlọrun li emi.*

*Awọn ole ti a kan mọ agbelebu pẹlu rẹ si n fi eyi na gún u loju bakanna.*

*Lati wakati kẹfa, ni okunkun ṣu bo gbogbo ilẹ titi o fi di wakati kẹsan.*

*Niwọn wakati kẹsan ni Jesu si kigbe li ohun rara wipe, Eli, Eli, lama Sabaktani? Eyini ni, Ọlọrun mi, Ọlọrun mi, eeṣe ti iwọ fi kọ ki silẹ?*

*Nigbati awọn kan ninu awọn ti o duro nibẹ gbọ eyi, nwọn wipe, ọkunrin yi npe Elijah.*

*Lojukanna ọkan .... ninu wọn si sare, o mu kànìnkànin, o tẹ ẹ bọ inu ọti kikan, o fi le ori ọ̀pá iye, o si fifun u mu.*

*Awọn iyooku wipe, Ẹ fi silẹ, ẹ jẹ ki a maa wo bi Elijah yoo wa gba a là.*

*Jesu si tun kigbe li ohun rara, o jọwọ ẹmi rẹ lọwọ.*

*Si wo o, aṣọ ikele tẹmpili si ya si meji lati oke de isalẹ, ilẹ si mi titi, awọn apata si sán.*

*.... Awọn isa oku si ṣi silẹ, ọ̀pọ̀ òkú awọn ẹni mimọ ti o ti sùn si jinde.*

*Nwọn ti inu isa òkú wọn jade lẹhin ajinde rẹ̀, nwọn si wá si ilu mimọ, nwọn si farahan ọpọlọpọ eniyan.*

*Nigbati balogun ọrún, ati awọn ti o wa pẹlu rẹ, ti nwọn nṣọ́ Jesu, ri iṣẹlẹ naa, ati ohun wọnni ti o ṣẹ, ẹ̀rú bà wọn gidigidi, nwọn wipe, Lootọ ọmọ Ọlọrun li eyi ìṣe.*

11 Ẹ jẹ ki a tẹ ori wa ba ni iṣẹju kan fun adura. Oluwa, a mọ pe iwọ ni Ọlọrun, ati lẹyin kika Ọrọ ọ̀wọ̀ ati Ọrọ̀ mimọ yi, a ṣi le ri pe Ẹda Rẹ ko ti yipada. Iwọ jẹ Ọlọrun nigba gbogbo. O dabi ẹnipe Jesu ko ni ni iranlọwọ kankan, pe awọn eniyan buburu, mu U a si gé E si wẹ́lẹ́wẹ́lẹ́ a si tutọ si I lara, a si fi ṣe ẹlẹya, a si gbé E kọ si ori igi-agbelebu, ẹjẹ n jade lati ara Rẹ, o n ku lọ; o dabi ẹnipe ko si iranlọwọ nibi kankan, titi ti oun funrara Rẹ kigbe sita, "Ọlọrun Mi, Ọlọrun Mi, eeṣe ti Iwọ fi kọ Mi silẹ?" Ṣugbọn O maa n wa si oju-iṣe ni akoko ti ko si ohunkohun tabi ẹnikẹni le ṣe ìrànwọ́.

A fi ye wa wipe, Oluwa, pe ti a ba ni odo kan ti a ko le la kọja, ti a ba ni òkè kan ti a ko le gùn, Ọlọrun ni agbara lati ṣe ohun ti ẹnikẹni ko lee ṣe. O jẹ akọṣẹ-mọṣẹ ninu iṣẹ yi. Nitori O mọ ìdí ti ọjọ Naa ni kalfari fi wa. Iwọ ti o jẹ Ọlọrun, Ẹniti o mọ ohun gbogbo, O mọ pe wakati yi yoo wà. Ṣugbọn nigbati eyi wá si imuṣẹ, lẹyin naa O fi hàn pe Iwọ ni Ọlọrun. O fi ẹniti o jẹ Ọga hàn.

12 O mi aye, ati awọn ẹni-mimọ ti wọn sun si abẹ́ ilẹ jade wa. O sọ oorun di dudu ni òru .... gẹgẹ bi i òkùnkùn ni òru, eyiti o fi hàn pe Iwọ ni Ọlọrun, ṣugbọn o dabi ẹnipe o wà ni idakẹjẹ fun igba pipẹ. Ẹ jẹ ki a ṣe ipinu lati inu èyí, pe niwọn igbati a ba n rin ninu Ẹmi, ti a si n dari wa lati ipasẹ ọwọ Ọlọrun, ohunkohun to wù ki o jẹ ìkùnà, síbẹ̀ a kọju si Kalfari. Ọlọrun yoo sọrọ ni igba ti o yẹ, ni akoko ti yẹ. Bayi Ọlọrun Baba wa, awa

yoo bere idariji ẹṣẹ wa. Awa yoo bere pé ki Ẹmi Rẹ ki o dari wa. Dari wa gẹgẹ bi ẹyẹ àdàbà ṣe dari ọdọ-aguntan. Jẹ ki a jẹ ẹni ti o n gbọ́ràn si ohunkohun ti o le ṣẹlẹ si wa, ti a si mọ eyi daju pé, Ọlọrun maa n ṣe ohun gbogbo ni daradara, a si mọ pe ohun gbogbo yoo dara.

Wa pẹlu wa ni òní ninu isin yi. A gbadura pe ki o gba awọn ti o wa ni ipo ti a fi le gba wọn la ti wọn si n wá igbala. Kún awọn ti wọn ni Iyè Ainipẹkun ti wọn n wa irú ohun bayi. A gbadura pe ki o wo awọn ti wọn n ṣe aisan sàn ati awọn ti a pọ́n loju ti wọn wá, ti wọn si n wa iwosan. A o si yin ọ fun èyí.

A bere ni orukọ ọmọ Rẹ, Olugbala wa, Jesu Kristi. Amin.

13 Bayi nigbati a n sọrọ ni owurọ yi, a fẹ pe akiyesi yin si àkorí ti mo yàn lati sọrọ lati ìnú rẹ. “Ọjọ Naa Ni Kalfari.” O dabi ẹnipe ko yẹ ni akoko yi, o yẹ ki o jẹ ni ọjọ Ẹti Rere. O yẹ ki a maa ranti Kalfari ni gbogbo ọjọ́. A si ti gbọ orişirişi nkan pupọ to nipa rẹ, a ti ka orişirişi nkan pupọ nipa rẹ. Awọn oniwaasu ti waasu nipa rẹ lati igbà ìbẹ̀rẹ̀ àkòkò. Awọn akọrin ti kọrin nipa rẹ ni gbogbo iran. Awọn wolii ti sọ asọtẹlẹ nipa rẹ̀ fun ẹgbẹrun mẹrin ọdun ṣaaju ki o to ṣẹlẹ, ati awọn wolii ọjọ ti oni wọn sọrọ nipa igba ti ọjọ yi ti ṣẹlẹ. O jẹ ọjọ ti o ṣe pataki.

O jẹ ọkan ninu awọn ọjọ ti o ṣe pataki julọ ninu gbogbo awọn ọjọ ti Ọlọrun ti da si orilẹ-aye. Ti o ba si jẹ wipe o ṣe pataki fun iran eniyan - Kalfari, mo rò pé o dara fun wa lati pada ki a si ṣe ayẹwo ki a si wo ohun ti ọjọ yi tumọ si fun wa. Nitori o dami loju pe ni akoko ti o ti fẹrẹ pari ti a n gbe inu rẹ yi, a n wa gbogbo ohun ti o ṣe pataki ninu Ọlọrun ki awa ki o le mọ̀, ati ohun gbogbo ti a le ṣe iwadi rẹ, a wà nibiyi lati kọ ọ. Ki a le ri ohun ti o wa fun wa, ati ohun ti Ọlọrun tị se fun wa, ki a si ri ohun ti o ti ṣeleri pe ohun yoo ṣe fun wa. Idi ti a fi wa si ile-ijọsin niyi.

14 Idi ti oniwaasu fi n waasu niyi. Idi ti o fi n kẹkọ ti o si n ṣe àṣàrò ninu Iwe-Mimọ ti o si n bẹbẹ fun ìmísí, o jẹ nitoripe o jẹ ojiṣẹ-ilu fun awọn eniyan Ọlọrun, o si n gbiyanju lati wa ohun kan ti yoo ṣe .... ti Ọlọrun yoo sọ fun awọn eniyan Rẹ̀, ohun kan ti yoo ràn wọn lọwọ. Boya yoo dá wọn lẹjọ ninu ẹ̀ṣẹ̀ wọn, ṣugbọn yoo jẹ iranlọwọ lati gbe wọn dide, ki wọn ki o le kọ ẹ̀ṣẹ̀ wọn silẹ, ki wọn si dide lati sin Oluwa. Ojiṣẹ Ọlọrun gbọdọ wa awọn nkan wọnyi.

15 Ti ọjọ yi bạ se pataki to bẹẹ gẹ, ọkan lara awọn ọjọ ti o lógo, ẹ jẹ ki a wo awọn ohun mẹta pataki ti ọjọ yi tumọ si fún wa. A le mu bi i ọgọrun púpọ̀. Ṣugbọn ni owurọ yi mo kan mú awọn ohun mẹta pataki ti a fẹ́ wò fun awọn akoko diẹ ti o kàn, ohun ti Kalfari tumọ si fún wa. Mo si gbadura pe yoo da gbogbo awọn ẹlẹṣẹ ti o wa nibiyi lẹ́bi, yoo jẹ ki gbogbo awọn eniyan mimọ lọ si ori eekun wọn, yoo jẹ ki gbogbo awọn ti o n ṣe aisan gbe igbagbọ rẹ soke si Ọlọrun ki wọn si rin jade pẹlu ìwósán, gbogbo ẹlẹ́ṣẹ̀ ni yoo ri ìgbàlà, gbogbo apadasẹyin ki wọn pada wa ki oju ara rẹ si ti i, ki gbogbo awọn eniyan mimọ si kún fún ayọ ki wọn si gba ireti tuntutn - ireti tuntun.

16 Ohun nla pataki ti Kalfari tumọ si fún wa, ati gbogbo agbaye jẹ́, o ni ìdáhùn fun ibeere ẹ̀ṣẹ̀ lẹẹkan ṣoṣo. A ri wipe eniyan jẹ̀bi ẹ̀ṣẹ̀, ẹ̀ṣẹ̀ si jẹ gbèsè ti ẹnikẹni kò lee san. Gbèsè, naa pọ to bẹẹ gẹ titi o fi jẹ wipe ko si ẹnikan ti o le san gbese naa. Mo gbagbọ daju pe Ọlọrun ti pinu rẹ pe yoo ri bẹ́ẹ̀ - pe gbese naa yoo pọ to bẹẹ gẹ ti ko ni fi si eniyan kankan ti o maa lee sanwo rẹ - ki Oun ba le ṣe eleyi funrara Rẹ!

Bayi, iku ni ere ẹ̀ṣẹ̀. Gbogbo wa ni a bi ninu ẹ̀ṣẹ̀ ti a dá ninu aiṣedede, a wá sinu aye yi a si n parọ́. Nitorina, gbogbo wa jẹ aláìyẹ, tabi wọn kò ri ẹnikankan ni aye yi ti o yẹ.

17 Ẹṣẹ ko si bẹrẹ ni ayé yi. Ẹ̀ṣẹ̀ bẹrẹ ni ọrun, Lusiferi, eṣu naa, jẹ ẹda Ọlọrun ti a ti da lẹbi nitori aigbọran rẹ̀ ṣaaju ki o to wá si aye. Ẹṣẹ bẹrẹ lọrun, nibiti Ọlọrun fi awọn angẹli si ati bẹẹbẹẹ lọ o gbe wọn lori oṣuwọn kannaa ti O gbé eniyan si. Lori imọ. Igi ìmọ̀ rere .... igi iye ati igi imọ rere, nibiti eniyan ti le ṣe iyan. Ati nigbati a fun Lusiferi ni anfani lati ṣe ìyàn rẹ́, o fẹ ohun miran ti o dara ju ohun ti Ọlọrun ni lọ. Ibiti wahala ti bẹrẹ niyi.

18 A si bèrè ìtanràn fun ẹ̀ṣẹ̀. Gbese rẹ si ni ikú. Iku ni èrè rẹ̀. Ati eyi jẹ .... a le lọ sinu ijinlẹ rẹ̀, nitoripe emi ko gbagbọ wipe sụgbọn iku kan ṣoṣo ni o wa. Iye kan ṣoṣo ni o wà. Mo gbagbọ wipe eniyan ti o ni Iye ainipẹkun ko le ku mọ laelae, mo si gbagbọ wipe iyapa ayeraye wa fun ọkan naa ti o dẹṣẹ. Nitori Bibeli sọ wipe, “Ọkan ti o ba dẹṣẹ, yoo kú dandan - ko ki n ṣe eniyan naa, ọkàn naa ti o dẹṣẹ. Nitorina Satani gbọdọ kú dandan, lati le pa a run patapata. Bi mo ti sẹ lodi si awọn ti o gbagbọ wipe gbogbo ẹda ni a o gbala ti wọn si sọ wipe a o gba Satani là! O dẹṣẹ, oun si ni oludasilẹ ẹ̀ṣẹ̀. Ọkan rẹ dẹṣẹ, o si jẹ ẹ̀mi. A o pa ẹmi yi run patapata ko si ni ku ohunkohun ninu rẹ̀.

19 Ati nigbati ẹ̀ṣẹ̀ wa sinu aye ni ibẹrẹ gẹgẹ bi i ìkuùkú dudu ti o sọkalẹ lati ọrun, o sọ aye di rudurudu. O sọ gbogbo ẹda aye, ati gbogbo ẹda Ọlọrun, sinu ìgbèkùn. Eniyan wa ninu ìgbèkùn ikú, àisàn, wahala, ibanujẹ. Gbogbo ẹ̀dá ni o ṣubu pẹlu rẹ. Ẹ̀ṣẹ̀ jẹ ọgun akunilórun ti o sọ gbogbo aye di rudurudu! Ati lẹhinnaa a si gbé wa sibiyi, ni aláìnírètí, nitoripe gbogbo ẹ̀dá ni aye ni o wa ni ìgbèkùn fún u, gbogbo ẹni ti a bi ni aye ni o wa ni igbekun rẹ. Nitorina o nira lati wa lati ibikan nibiti ko si ẹ̀ṣẹ̀. Ko le jẹ wipe yoo wa lati àyé.

Ko si ẹnikankan wa ti o le ra ẹnikeji rẹ pada. O gbọdọ jẹ pe yoo wa lati ọ̀dọ̀ ẹlomiran. Nitorina, nigbati eniyan loye pe a ti ya ohun nipa kuro lọdọ Ọlọrun rẹ, o di alárinkiri. Wọn sọkun, wọn kigbe, wọn ṣe lààlàá, wọn di alarinkiri laarin awọn oke, ati ninu awọn aṣalẹ, wọn n wa ilu kan ti olupilẹṣẹ rẹ ati ẹniti o kọ ọ jẹ Ọlọrun. Nitori o mọ wipe ti oun ba pada si iwaju Ọlọrun, oun yoo ba A sọrọ nipa gbogbo rẹ. Ṣugbọn ko si ọna lati pada. O sọnu, ko mọ ọna ti oun yoo ya si. Nitorina o kan jade lọ o n rin kiri, o n gbiyanju lati wa ibiti oun yoo ti ri ọna ti o pada lọ si ibẹ! Ohun kan ninu rẹ sọ fun un wipe o wa lati ibikan ti o jẹ pipe.

20 Ko si ẹnikẹni ninu àpéjọpọ̀ ti a le fi oju-ri ni owurọ yi, tabi ninu àpéjọpọ ti a ti n gbọ ohùn nikan eyiti yoo lọ kaakiri gbogbo orilẹ-aye, ko si ẹnikẹni nibiyi tabi nibo miran, ṣugbọn ti yoo maa wa pipe naa. Nigbati iwọ ba san awọn owo ti o yẹ ki o san, iwọ yoo ro pe gbogbo rẹ ti pari. Nigbati iwọ ba san owo yi, lẹhin naa ẹlomiran yoo tun ṣe aisan ninu ẹbì rẹ. Nigbati aisan yi ba lọ, lẹhin naa owo ti iwọ yoo san yoo tùn pọ̀ si. Ohun akọkọ ti iwọ yoo ri ni wipe, irun ori rẹ ti n di funfun, ati lẹhin naa iwọ yoo nifẹ lati pada di ọ̀dọ́. Ohun kan si maa n wa nigba gbogbo, nigba gbogbo, nitori iji ẹ̀ṣẹ̀ naa. Sụgbọn ninu ọkàn rẹ, nitoripe iwọ n wa eyi, o fi hàn pé pipe kan wa nibikan. Nibikan ohun kan wà.

21 Idi niyi ti o fi jẹ wipe ni ọpọlọpọ ìgbá ni òní ẹlẹṣẹ si n rin kaakiri. Ọdọmọbinrin kekere ti o lẹ́wà kan yoo gé irun ori rẹ ti a fi n ṣe idánimọ rẹ ki oun ba le di olokiki, yoo kun oju rẹ ki oun ba le rẹwa si, yoo wọ asọ ti yoo fi gbogbo orikèríkè ara rẹ̀ hàn, nitoripe ohun yi nikan ni o le ri, o n wa ibikan, o n gbiyanju lati wa ohun kan lati pada si ibiti oun - nigbati yoo jẹ ki awọn ọkunrin súfe si i, wọn yoo juwọ́ si i, wọn yoo ṣe ìfẹ́kùfẹ́ pẹlu rẹ. Ọdọ́mọkùnrin yoo ṣe bakannaa si obinrin. Wọn yoo gbiyanju pe ki awọn dùn un wo si obinrin naa. Awọn alábàgbé yoo kọ ile kan wọn yoo si gbe e kalẹ ni ọna kan nitoripe ki ile yi le dara diẹ ju ti ile alabagbe rẹ lọ. Eleyi maa n ṣẹlẹ nigba gbogbo! A n wa ohun kan, ohun kan si n tẹsiwaju lati goke diẹ ju eleyi lọ.

22 Ọdọmọbinrin yoo ri ọdọmọbinrin miran ti o lokiki ju u lọ. Alábàgbé yoo ri ilé miran ti o dara ju ile ti ara rẹ lọ.

Obinrin kan yoo ri obinrin miran ti o wọ aṣọ ni ọna ti o dara ju bi o ti ṣe maa n wọ aṣọ lọ. O jẹ ohun kan ninu wa ti o n wa ohun kan, eyi si fi hàn pe a ti sọnù. A n wá ohun naa ti yoo mú wa pada lọ si ibi itẹlọrun naa, ti yoo kún ebi oungbẹ naa ti o wa ninu wa, ṣugbọn o dabi ẹnipe a ko ti ri i.

Awọn eniyan gbiyanju rẹ ni gbogbo igba iran. Wọn sọkun fun un. Wọn kigbe. Wọn ṣe ohun gbogbo ti wọn mọ pe awọn le ṣe, ṣugbọn sibẹ wọn ko ri i, wọn n rin kiri ninu aye yi.

23 Nigbẹyin ni ọjọ kan - eyi ni ọjọ naa ni Kalfari - nibẹ ni Ẹnikan ti sọkalẹ wa lati inu ogo, ẹnikan ti orukọ rẹ jẹ Jesu Kristi ọmọ Ọlọrun, ẹniti o wá lati inu ògo, a si da Kalfari silẹ. Eyi ni ọjọ naa ti a san owo naa, a sị se idahun fun gbogbo ibeere ẹ̀ṣẹ̀ titi laelae, a si ṣi ọna silẹ fun awọn nkan wọnyi ti ebi rẹ n pa wa ti a si n pongbẹ fún. O mu ibi itẹlọrun wá.

Ko si ọkunrin kankan ti o de Kalfari ti o si ri bi o tị se ri, ti yoo ri bakanna mọ́. Gbogbo ohun ti o le nifẹ lati ni tabi ti o n pongbẹ fún gbogbo rẹ ni a ba pade nigbati o ba de ibiyi. O jẹ ọjọ pataki kan, o si jẹ ohun ti o ṣe pataki, o mi gbogbo aye! O mi gbogbo aye eyiti a kò ti mi aye bi eleyi ri.

Nigbati Jesu ku ni Kalfari ti o si san igbese ẹ̀ṣẹ̀.

24 Aye ẹ̀ṣẹ̀ yi ni okùnkùn biribiri! Oorun lọ silẹ ni ọsan gangan. O ni idamu gidigidi, awọn apata mì tìtìtìtì, awọn okè ya lulẹ̀, ati awọn òkú jade wa lati inu iboji. Kini ohun ti o ṣe? Ọlọrun pari gbogbo rẹ ni Kalfari. O pa ẹranko naa ti a n pe ni Satani lara titi laelae.

Bayi, lati ìgbà naa ni o ti ni oró ninu, nitoripe O mu imọlẹ wá si iran ọmọ eniyan; gbogbo eniyan ni o si mọ pé ti a ba pa ẹranko kan lara o maa n ni oró si i .... o n fà kaakiri pẹlu egungun ẹyin rẹ ti a ti fọ́.

Bayi, A ti ṣẹgun Satani ni Kalfari. Ayé jẹri pe bẹẹni o ri. Owo nla naa ti a ko ti san iru rẹ rí, Ẹni kanṣoṣo naa ti o le san án, sọkalẹ wa o si ṣe eyi ni Kalfari. Ibiyi ni a ti san owo nla naa. Eyi jẹ ọ̀kan ninu awọn nkan wọ̀nyí.

25 Ọlọrun beere fun eyi. Ko si eniyan kankan ti o yẹ, ko si ẹni kankan ti o ká oju-oṣuwọn, ko si ẹnikankan ti o le e ṣe. Ọlọrun funrara Rẹ sọkalẹ wa a si sọ Ọ di eniyan, O si gbe igbesi-aye eniyan labẹ ifẹ eniyan, a si kan An mọ agbelebu. Ati nibẹ, nigbati Satani ro pe oun ko le e ṣe e, oun ko le la a kọja - Ó la Gesthsemane kọja ati gbogbo idanwo ti ẹnikẹni le e là kọja. O la a kọja bakanna gẹgẹ bi i gbogbo eniyan; ṣugbọn O san gbese naa; ohun ti o sọ aye si okunkun niyi.

Gẹgẹ bi òògùn ti a fi maa n kun eniyan lórun ti o ba fẹ ṣiṣẹ abẹ. Nigbati dọkita ba fun eniyan kan ni oogun ti a fi maa kun eniyan lórun .... o ma jẹ ki o kọ́kọ́ sùn patapata ṣaaju ki o to ṣe iṣẹ-abẹ yi. Ati nigbati Ọlọrun ṣe iṣẹ-abẹ fún ìjọ, aye gba òògùn-orun. G̀iri mú ayé.

Abájọ, Ọlọrun, ninu ẹran-ara eniyan, n kú lọ. O jẹ akoko ti ayé ti fojusọna fun, síbẹ̀ ọpọlọpọ ninu wọn ko mọ eleyi. Gẹgẹ bi o ti ṣe ri ni oni yi, ọpọlọpọ ni o n wa awọn nkan wọnyi, ati sibẹ wọn ko dá awọn nkan wọnyi mọ̀. Wọn ko loye ọna àbáyọ. Wọn si n gbiyanju lati ṣe ifẹkufẹ ati awọn ohun aye, wọn n gbiyanju lati wa ọna àbáyọ.

26 Ọpọlọpọ àmì-oju-pátákó ni o wà ti o n tọka si ọjọ́ naa -ọpọlọpọ ojiji. A ti fi òjìjì rẹ hàn lati ara ọdọ-aguntan, lati ara akọmalu, lati ara ẹyẹ àdàbà, ati gbogbo awọn nkan wọnyi, ṣugbọn sibẹ a ko le fọ ọ. Wọn ko le fọ́ ẹ̀wọ̀n ikú naa! Nitori Satani ti gba ayé. Apata naa ti o ti rin kọja lori rẹ rí lori ilẹ ayé, sulfuri (okuta-ina) ti n jó-Lusiferi jẹ ọmọ owurọ o si rin lori ilẹ-ayé nigbati o n ru jade bi i ina - awọn okuta kannaa ti wọn ti tutù, nigbati Jesu kú ni Kalfari, ti o fi agbara jade kuro ninu aye. Owo naa ti a san, a si já ìdè Èṣù naa.

27 Ọlọrun ti pada fi si ọwọ eniyan, ọna ti yoo fi pada si ohun ti o n wá. Ko nilo lati sọkún mọ. Nigbati o fọ egungun ẹyin Satani ni Kalfari - egungun ẹyin ẹ̀ṣẹ̀, ti aisan - ti o si mu gbogbo ẹda alaaye ni ori-ilẹ ayé pada wa si iwaju Ọlọrun ti a si dari gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ ji.

Hallelujah! A ti dari ẹ̀ṣẹ̀ wa ji wa! Eṣu ko le diwa lọna mọ́ kuro lọdọ Ọlọrun! Ọna nla kan wa ti a ṣe, ẹ̀rọ ibanisọrọ kan wa ti a gbe sibẹ, waya kan wa ti o lọ sinu ògo. O mu gbogbo awọn ti o de ibi waya yi wọle.

Ti eniyan ba kún fun ẹ̀ṣẹ̀, yoo mu u lọ si ibi waya yi. A le dari gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ yi jin in! Ko ki n ṣe eyi nikan, ṣugbọn a ti sanwo ẹ̀ṣẹ̀ yi! O ko nilo lati sọ wipe, “Emi jẹ aláiyẹ.” Dajudaju iwọ jẹ alaiyẹ. Iwọ ko le yẹ laelae. Ṣugbọn Ẹniti o yẹ kan gba ipo rẹ! A ti tú ọ silẹ! O ko nilo lati jẹ alarinkiri mọ́. O ko nilo lati jẹ ọkunrin ti o n wa afẹ́ ayé mọ nita nibiyi lori ilẹ̀ ayé. Nitori,

Ìsun kan wa to kún fun ẹjẹ;

Ti o ṣàn lati ìhà Emmanuẹli;

Ẹlẹṣẹ m'okun ninu rẹ,

O bọ ninu ẹ̀bi.

O ko nilo lati ṣegbe. Opopo kan wa, ati ọna kan, a si n pe ni ọna iwa-mimọ, awọn aláìmọ́ ki yoo kọja lori rẹ.“ Nitori o kọ́kọ́ wa si ìsun naa, lẹhin naa o lọ si opopo naa.

28 O fọ agbara Satani. O ṣi ile-tubu ti ọrun apadi, ki gbogbo eniyan ti a tìlẹ̀kun mọ́ ni aye yi - ninu túbú - ti wọn n bẹru pe ti oun ba ku, kini ikú yoo jẹ́ sí oun .... Ni Kalfari O ṣi awọn ilẹkun ile-tubu yẹn O si jẹ ki gbogbo awọn ti a mu ni igbèkùn gba ìtúsílẹ̀. Ẹṣẹ ko le fa ọ lulẹ mọ. O ko nilo lati fi ara rẹ silẹ fun ẹ̀ṣẹ̀ mọ́, o ko nilo lati fi ara rẹ silẹ fun ọti-mimu, siga-mimu, tẹtẹ-tita, irọ-pipa.

O le jẹ olootọ, ẹni-mimọ ati olododo; Satani ko si le ṣe ohunkohun nipa rẹ̀, nitoripe o ti di waya naa mú! Waya ìyè naa eyiti o ni ipinlẹ ninu apata ayeraye. Ko si ohunkohun ti o le mi ọ kuro ninu rẹ. Ko si afẹfẹ ti o le mi ọ kuro ninu rẹ̀. Ko si ohunkohun, iku paapa funrararẹ, ko le yà wà nipa kuro ninu ifẹ Ọlọrun ti o wa ninu Kristi Jesu.

29 Ohun ti Kalfari jẹ niyi. A tu awọn ọkunrin ti o wà ni ìgbèkùn silẹ. Awọn ọkunrin ti wọn wa labẹ ẹ̀ru ikú lẹẹkan ri wọn ko ni bẹru ikú mọ́. Ọkunrin kan ti n pongbẹ fun ìlú kan eyiti Ọlọrun tẹ̀dó ti o si kọ́, o le rin ni opopo naa, ki o si gbe ojú rẹ soke si ọrun, nitoripe o ti gba itusilẹ. Hallelujah, a ti ra a pada! Ko nilo lati jẹ alarinkiri mọ́, nitori ọ̀nà wà ti iwọ yoo fi mọ̀ boya iwọ tọ́ tabi iwọ ko tọ́. Ọlọrun fun wa ni iye. Gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ wa ti lọ. Ọjọ naa ni Kalfari ni o san gbèsè naa.

Nigbati a ri gbogbo eyi, abajọ ti akọrin naa fi kọ ọ pe;

Apata ti o ya lulẹ ati oju-ọrun

To ṣú dúdú,

Olugbala tẹ ori Rẹ ba O si kù.

Asọ ileke ti o faya naa fi ọna naa hàn

Si ayọ̀ ọ̀run ati ọjọ aìlópin.

30 Abrahamu ko nilo lati maa rin kiri ilu mọ ki o si maa wá ìlú kan. Ẹlẹṣẹ kò nilo lati maa ronú mọ̀ ki o si maa ro boya a o gba oun la tabi a ko ni gba a là. Ọkunrin alaisan ko nilo lati maa ronu mọ pe ṣe oun yoo ri iwosan tabi oun ko ni ri iwosan gbà. Aṣọ ìkéle naa ti a ṣi ni ọjọ naa ni Kalfari ti fi ọna si iṣẹgun patapata hàn! Ọlọrun fún wa ni agbara Ẹmi Rẹ lati gbe igbesi aye iṣẹgun lori gbogbo awọn nkan wọnyi, O si sọ fun wa pe ki a gba A gbọ nikan. Eleyi sẹlẹ ni ọjọ naa ni Kalfari.

Ko si ọjọ ti o dabi ọjọ yi ri. ko si ni si ọjọ ti yoo ri bi i rẹ̀. Kọ se pataki mọ́. A ti san owo rẹ! A si ti ra wa pada. A dupẹ lọwọ Ọlọrun! A ti rà wa pada.

O ko nilo lati jẹ alarinkiri mọ. Ko si iyemeji mọ̀ nipa rẹ. Gbogbo rẹ̀ ni a ti mú lọ. Aṣọ-ikele naa ti ṣi iboju naa, a si ti wa ni opopo naa. Lati ma ṣe iyemeji mọ́, ṣugbọn ki a gbagbọ, ki a si maa rin lọ. A o rin lọ si iwaju Ọlọrun tààrà.

31 Abrahamu mọ̀, awọn iyoku si ọ̀ pẹ̀lú, pe nigbati wọn n wa ilu naa, wọn mọ̀ pe awọn wá lati ibikan. Ohun kan ti ṣẹlẹ. Wọn n gbe ni aye ti o ti dàrú. Ilẹ-rírì wá, iji dé, ogun ati ipaniyan. Ìkòokò ati ọdọ-aguntan n jẹ ara wọn .... tabi, Ìkòokò n jẹ akọmalu, kiniun si n jẹ ẹgbọrọ maalu. Eleyi kò tọ́. Ohun kan tị sẹlẹ. Wọn mọ pe ohun kan ti kùnà. Awọn ọkunrin - arakunrin n pa arakunrin, baba n pa ọmọ, ọmọ n pa baba. Ohun kan ti kuna. O n darúgbo si, o n ku lọ, o n gbó lọ, àisàn ti wa ni ara rẹ, o wa ninu igbekun. Awọn igi n dagba, ṣugbọn wọn yoo kú. Wọn kú. Awọn oke yipada. Awọn òkun gbẹ. Ko si omi. Ohun kan ti kuna! O si n wá ibikan, ilu kan nibiti awọn nkan wọnyi kò ti ni ṣẹlẹ mọ laelae. O mọ̀ pe ti ohun ba le pada si iwaju Ẹni naa ti O mu gbogbo rẹ tọ́, oun yoo ba A sọrọ nipa Rẹ̀.

32 Oo iru anfani wo niyi, awọn ẹlẹṣẹ, o jẹ owurọ yi ni o mọ pe ọna abayọ wa bayi. Ọjọ naa ni Kalfari ni o ṣi ọna naa. Nitori awọn baba igbagbọ wa A, wọn wa A. Kalfari ni o fifiun ọ lọ́fẹ!

Bawo ni iwọ yoo ṣe kọ̀ lati gba a? Bawo ni iwọ yoo ṣe kọ ọ ki o si lọ darapọ mọ ẹgbẹ́ ijọ ẹlẹkọ adamọ? Bawo ni iwọ yoo ṣe kọ ọ silẹ ki o si fi ohun miran dipo rẹ? awọn afẹ́ aye? Kini idi ti iwọ ko fi gba a?

Aṣọ ìkéle naa ti a ṣi mu eniyan pada wa si iwaju Ọlọrun laisi ẹ̀ṣẹ̀ kankan ni ọrun rẹ, o si gbe ọna kan ka iwaju rẹ̀ ti o n tọka si ohun ti o n wá - ọ̀run, ogo, alafia, ayeraye, ohun gbogbo wa ni iwaju rẹ̀.

33 Ọjọ yi ni Satani ni ìkọlù alagbara. Eleyi pari ohun gbogbo. Mo si le e ri I nibẹ. O jẹ Ọdọ-aguntan ti Edeni, lati ojiji àkọ́kọ́ ti o jade wá lati ibẹ̀, nigbati Abẹli nipa igbagbọ rubọ ti o ṣe itẹwọgba si Ọlọrun ju Kaini lọ.

O ti maa so okùn igi girepu mọ ọdọ-agutan kan lọrun, o si fa a lọ si ibi apata, yoo mu apata kan ni ọwọ rẹ lati fi ge e ki o si yi ori rẹ sẹyin, ki o si ge e ki o si rẹ ẹ titi tị emi yoo fi jade lara rẹ̀. Ẹjẹ ara rẹ yoo si da si iru ara rẹ̀, o wẹ̀ ninu ẹjẹ ara rẹ! O jẹ ojiji.

Ṣugbọn ni ọjọ naa ni Kalfari, ko si ọdọ-aguntan ti aye yi, ṣugbọn o jẹ Ọdọ-Aguntan ti Ọlọrun ni o n kú lọ - ti o n wẹ ninu ẹjẹ ara Rẹ̀. A rẹ Ẹ, a si ge E, a si naa Án a si tutọ si I ni ara, a si gba A loju a si lu U, ati ohun gbogbo nipasẹ ayé! Ẹjẹ si n da lati ara Rẹ.

34 Nigbati Ọdọ-aguntan Abẹli kú, o ku o si n sọ èdè ti Abẹli ko mọ itumọ rẹ. O n sẹjẹ. Ati nigbati ọdọ-Aguntan Ọlọrun naa kú ni ọjọ naa ni Kalfari, O sọrọ ni ede ti ẹnikẹni ko mọ itumọ rẹ. "Ọlọrun Mi, Ọlọrun Mi, eeṣe ti Iwọ fi kọmi silẹ?" O jẹ Ọdọ-Aguntan Ọlọrun, eyiti a ge si wẹ́wẹ́, a ge E.

Oun ni ọdọ-Aguntan naa ti Abẹli ni ninu ọkàn rẹ̀, nigbati o ri ìrú ọmọbinrin naa ti a ti ṣeleri. Oun ni Ọdọ-Aguntan naa ti Daniẹli ri eyiti a "gbẹ laisi ọwọ́ lati ara Àpáta." Oun ni "Kẹkẹ́ naa ti o wà ni aarin kẹkẹ́" fun wolii naa. Gbogbo ohun ti wọn ti ri gẹgẹ bi apẹẹrẹ ni o farahàn ni ọjọ naa - ọjọ naa ni Kalfari. Eleyi mu ohun nla naa wọlé. Eyiti o fọ́ ẹ̀yín Satani.

35 Ni akọkọ, a gbọdọ wá ohun ti ọjọ naa tumọ si. Ni ẹẹkeji, a gbọdọ ri ohun ti ọjọ naa ṣe fun wa, ohun ti o ṣe fún wa, Nisisiyi ni ẹ̀kẹta, ẹ jẹ ki a wo ohun ti o yẹki awa naa pẹlu ṣe fun ọjọ naa, ohun ti o yẹ ki a ṣe.

Ni àkọ́kọ́, ẹ jẹ ki a wo o, nitori o jẹ ọjọ nla - ọjọ ti o tobi ju gbogbo ọjọ lọ. A san gbese ẹ̀ṣẹ̀. Agbara Satani ni a fọ́. Ati nisisiyi mo fẹ ki ẹ ri ohun ti o yẹ ki awa naa pẹlu ṣe fun ohun ti O ṣe fun wa.

Bayi, fun ohun ti o ṣe, nigbati Jesu kú ni Kalfari, ko ki n ṣe pe o san gbese ẹ̀ṣẹ̀ wa nikan, ṣugbọn o san gbese naa, O si lana silẹ pe ki a le e tẹle E. Nitori àwa, gẹgẹ bi Adamu ti o ṣubu ti a si ti ra pada .... Gẹgẹ bi Ẹmi ṣe dari Adamu - Adamu akọkọ - nipasẹ Ẹmi, ti o ni akoso lori gbogbo ẹ̀dá, lẹhin naa awa Adamu keji, tabi, ọkunrin ti ayé - a ti ra wa pada nipasẹ Kristi lati ọjọ naa ni Kalfari, ki a ba le tẹle E.

36 Bayi, nigbati o kú ni Kalfari, O la ọna silẹ O fi Ẹmi naa silẹ, Ẹmi Mimọ, ti a ran pada si ayé fún iwọ ati emi ki a le gbé nipasẹ rẹ. Ohun ti Kalfari tumọ si fun wa niyi, lati tẹlẹ E.

Ni akọkọ, wo o. Ri ohun ti O ṣe fun wa, ati nisisiyi kini ohun ti o yẹ ki a wạ se ni bibu ọla fun eyi. Kini ohun ti iwọ ati emi mi yoo ṣe? Bayi, a sọ wipe, "O dara mo mọ rírì èyí. Eleyi dara." Ṣugbọn a ni lati gba a. Lati gba a ni ki a gba ẹniti Oun jẹ́, Kristi, ninu ọkan wa. Lẹhin naa a bọ́ kuro lọwọ ẹ̀ṣẹ̀. Nitorina, ko si iru ẹ̀ṣẹ̀ kankan ti o wa ni ọrun wa rara. Ọlọrun .... O dabi ẹnipe a kò ti dẹṣẹ ri.

Ẹbọ pipe naa ti sọ wa di pípé. Nitori Jesu sọ wipe, "Nitorina ẹ jẹ́ pipe, gẹgẹ bi Baba yin ọrun tị se jẹ pipe." Lẹhin naa ko si ohun miran ti a o ṣe, ṣugbọn a sọ wa di pipe niwaju Ọlọrun.

37 Bayi ibiti a ti sọ ipo wa nù niyi. Ti a ko ba kíyèsára, a gbiyanju lati wo ohun ti a jẹ sẹyin, ati niwọn igbati a ba wọ eyin si ohun ti a jẹ, ẹbọ naa ko ni itumọ kankan si wa. Oo, ṣe iwọ kò ri ni, ijọ? Emi kò ni gbiyanju iṣẹ naa, emi ko le e ṣe e, bẹni iwọ ko lee ṣe e. Ko nilo ki a gbiyanju. O ti ṣegbe ni ibẹrẹ niwọn igbati o ba n wo ohun ti o tị se. Ṣugbọn ma wo ohun ti o ti ṣe, wo ohun ti ọjọ naa ni Kalfari ṣe fun ọ!

O san gbese rẹ. O dahun gbogbo ibeere. "Bi ẹ̀ṣẹ̀ yin ba ri bi ododo, won yoo funfun bi òjò-didi, bi nwọn pọn bi alari, yoo funfun bi irun-aguntan." Lẹhin naa ẹ ko ni ẹ̀ṣẹ̀ rara. Ẹ jẹ pipe laini ẹ̀ṣẹ̀. Ohunkohun to wù ki ẹ ti ṣe tabi ti ẹ ṣe, ẹ ko ni ẹ̀ṣẹ̀ kankan! Niwọn igbati ẹ ba ti gba Jesu Kristi gẹgẹ bi Olugbala yin, a ti dari ẹ̀ṣẹ̀ yin ji. Ohunkohun ti a ba ti dari rẹ ji a ti fi ji a si ti gbagbe nipa rẹ.

Lẹhin naa kini ohun ti o ṣe? O fun ọ, lẹhin igba yẹn, Ẹmi Rẹ lati tẹle E, ki o si ṣe gegẹ bi Oun naa ti a ṣe, fun awọn ẹlomiran, ti wọn ti n tẹle E.

38 O kan jẹ ọkunrin kan, ọkunrin pipe naa. O fi Ẹmi Rẹ lélẹ̀, O si fi apẹẹrẹ silẹ fun wa.

Bayi, kini ohun ti o yẹ ki a ṣe? Nisisiyi, ohun àkọ́kọ́ ti mo fẹ́ sọ ni wipe: Jesu ko gbe igbe-aye fun ara Rẹ̀. O gbé igbesi aye Rẹ fun awọn ẹlomiran. Eyi jẹ Iye ainipẹkun ni pípé. Nigbati o ba sọ wipe o lọ si ile-ijọsin ti o sị se awọn ohun ti o dara, eyi dara. Ṣugbọn ti o ba n gbe igbesi aye rẹ fun ara rẹ, iwọ kò ni ìyè ainipẹkun. Iye ainipẹkun tumọ si pe ki o gbe igbesi-aye fun awọn ẹlomiran.

O fi idi eyi mulẹ nigbati o wá ninu ọdọ-Aguntan Ọlọrun. O gbé O si ni ìyè ainipẹkun nitoripe ko gbe igbesi-aye fun ara Rẹ, O gbe igbesi-aye fun awọn ẹlomiran. Iwọ yoo si gba Iye Ainipẹkun nipasẹ gbigba ọjọ̀ naa, iwọ kò si ni gbe igbesi-aye fún ara rẹ mọ, iwọ yoo gbe igbesi-aye fun awọn ẹlomiran.

39 Ẹnikan sọ wipe, "Bawo ni iwọ yoo ṣe duro ki o si gbà pe ki awọn eniyan maa pe ọ ni oriṣiriṣi orukọ buburu bi eleyi?" Iwọ kò gbe igbesi-aye fún ara rẹ. O n gbe igbesi-aye fún awọn ẹlomiran ki iwọ le e ra ọkunrin náà pada. Iwọ yoo di awọn ọmọkunrin; ati ohun buburu nipa rẹ ni wipe ijọ ti gbàgbé pé awọn jẹ awọn ọmọkunrin. Ẹyin jẹ awọn ọmọkunrin. Ẹyin n gba ìpò Kristi. Ẹyin jẹ awọn ọmọkunrin, nitorina maṣe gbé igbesi-aye fún ara rẹ, gbe igbesi ayé fun awọn ẹlomiran.

"O dara, Arakunrin Branham, mo le gbe igbesi-ayé fun arakunrin yi nitoripe o daju pe ọkunrin daradara ni." Eleyi ko ri bẹ. Gbe igbesi-aye fun ọkunrin naa ti o korira rẹ! Gbe igbesi-aye fun ọkunrin naa ti yoo pa ọ ti wọn ba le e ṣe e. Ohun ti wọn ṣe fún Un niyi. Wọn pa A, O kú ki Oun ba le e gbà wọn. Eyi ni ìyè ainipẹkun. Nigbati o ba ni eyi ninu ookan àyà rẹ, iwọ ti kọju si ọ̀run nigba naa. Sụgbọn iwọ ti fi awọn nkan ti ara rẹ silẹ. O fi wọn sílẹ̀ gẹgẹ bi aguntan tị se maa n fi irun-ara rẹ̀ sílẹ̀. Iwọ yoo kọju si Kalfari.

40 Mo lero pé eleyi yoo ṣe ìrànwọ́ fun ọ lati dé ìbìkan! .... Eleyi ni Àgọ́-Ijọsin naa, ohun ti o yẹ ki gbogbo eniyan ṣe niyi - ohun ni pé ki o mọ irú ẹni ti o jẹ, ati kini ìdí ti o fi waye.

Ijọ ko lọ si ile-ijọsin lati lọ lo awọn ohun-elo orin nikan, ki o si kọ awọn orin. Ijọ jẹ ibikan ti a ti n bani wi. Idajọ bẹrẹ lati ile Ọlọrun. A gbọdọ ka ara wa si òkú ki a si wà laaye si Kristi. Lẹhin naa O lànà pe ki àwa fi ara wa silẹ fun iṣe-isin Rẹ̀ lati maa tẹle E. Ti a ba tẹle E, a o darí iru igbesi-aye ti O darí. Eleyi jẹ iyanu. Jesu sọ ọ O si sọrọ nipa rẹ .... Ẹ jẹ ki emi kàn fun yin ni ayọka diẹ lori rẹ̀. Tẹti silẹ dáada. Maṣe padanu rẹ̀!

41 Jesu sọ wipe ni ọjọ naa Oun yoo ṣe ipinya fun awọn eniyan gẹgẹ bi aguntan ati ewúrẹ́, oun yoo si sọ fun awọn ewúrẹ́, "Ẹ duro si apá òsì," ati si awọn aguntan, "Ẹ duro si apa ọ̀tún." Yoo si sọ fún awọn ewurẹ pe, "Ẹ yàgò kuro ni ọ̀dọ̀ mi, nitoripe nigbati ebi n pa Mi, ẹyin ko fun mi ni ounjẹ. Mo wa ninu túbú, ẹyin ko si wa ṣàbẹ̀wò si mi. Mo wà ni ìhòhò, ẹyin ko fi aṣọ bòmí. Òngbẹ n gbẹ mi, ẹyin ko fun mi ni omi. Mo n ṣe àisàn, ẹyin ko sàbẹ̀wò si mi. Nitorina ẹ kuro lọdọ mi," Ati si awọn aguntan, O wipe, nigbati ebi n pa mi, ẹ fun mi ni ounjẹ. Nigbati mo wa ni ihoho, ẹ daṣọ bomi. Mo n ṣe aisan, ẹ sị se iranṣe fun mi." Si ṣe akiyesi, maṣe kuna lati ri eleyi, ijọ! Ẹ fi eleyi pamọ́ sinu ọkàn yin titi laelae! A ko ṣe é pẹlu ipinu. Awọn eniyan ṣe gẹgẹ bi i ojúṣe. Ọkunrin kan ti o fun ọ ni ohun kan tabi ohun miran nitoripe o yẹ ki o ṣe e, eniyan ti o fun ọ ni ounjẹ nitoripe o yẹ ki o ṣe e, o ni ìwà imọtara-ẹni-nikan. O yẹ ki o jẹ igbé-ayé rẹ, o yẹ ki o jẹ iwa rẹ.

42 Ó ya awọn aguntan yi lẹnu ti wọn fi sọ wipe, "Oluwa, nigba wo ni ebi n pa ọ ti a ko si fun ọ ni ounjẹ .... nigbawo ni ebi n pa ọ ti a si fun ọ ni ounjẹ? Nigbawo ni o wa ni ihoho, ti a si fi aṣọ bo ọ? Nigbawo ni ongbẹ n gbẹ ọ, ti a si fun ọ ni omi? Nigbawo ni o ṣe aisan, ti a sị se iránṣẹ̀ fún ọ?" O jẹ ohun ti a ṣe laìrò-tẹlẹ̀ - pẹlu ìfẹ́. O jẹ igbe-aye wọn ti wọn n gbe jade.

Ọlọrun, jẹ ki awọn eniyan ri ohun ti Kalfari ṣe fun wa. O jẹ ohun ti o sẹlẹ funrararẹ. "Nigbawo nibo ni o wà .... Oluwa. Awa kò mọ eleyi."

Woo ohun ti Jesu yipada ti O si sọ wipe "Niwọn igbati ẹ ba tị se e fun awọn wọnyi, ẹ tị se fun mi." Igbe-aye ti kò ni ìmọtara-ẹni-nikan. Ko nilo ka ro nipa rẹ lẹẹmeji, ko nilo ka ronu nipa rẹ̀, ṣugbọn o ti di òkú si àwọn ohun aye yi, o si wa laaye ninu Kristi, o si n rin ni opopo naa, gbogbo awọn nkan wọnyi jẹ bárakú rẹ. O kàn

maa n ṣe wọn.

43 O ko ni sọ wipe “Bayi Ọlọrun ko fẹ ki emi ṣe eyi.” Ko ki n ṣe bẹẹ. O jẹ ipa lara Rẹ̀. Ẹmi Rẹ wa ninu rẹ, o si huwa bi i tiRẹ. Ṣe oye yi ye ọ? “Ọna kan wa ti o dara loju eniyan, ṣugbọn opin rẹ jẹ ọna ikú.” Ko ki n ṣe gbogbo awọn ti o sọ wipe, Oluwa. Oluwa, ni yoo wọlé; ṣugbọn awọn ti o ṣe ifẹ Baba mi.“ - ti o wa lati inu ọkàn wọn, laifi ipá muni.

Bayi, ọjọ naa ni Kalfari, san gbogbo gbese ki àwa le e ri bi eleyi. Kò sọ wipe, “Ṣe o mọ, Jones ti o jẹ opó ni ìgbà kan ko ni èédú, mo si jade lọ mo si ra eedu fun un.” tabi, “mo sọ fun ọ, mo ri arakunrin kan ti o nilo aṣọ oyinbo súutù, mo si lọ mo si ra aṣọ oyinbo súutù yi fún un. Fi ibukun fun Ọlọrun mo jẹ̀ Kristẹni.” Oo, akiika. O jẹ́ imọtara-ẹni-nika, òtòṣi, àre eniyan! O jẹ alágàbàgebè. Maṣe jẹ ki ọwọ ọ̀tún mọ ohun ti ọwọ òsi n ṣe, tabi ki osi mọ ohun ti ọ̀tún n ṣe.

Kàn kú sinu Kristi titi ti iwọ yoo fi ṣe e ni ọnakọna. Ó jẹ ìwà-ẹ̀dá rẹ, o jẹ bárakú rẹ. Iwọ ṣe e ni ọnakọna. O jẹ ìyè ti o n gbé ninu rẹ. O ti jọwọ gbogbo ara rẹ patapata fun Ẹmi naa, o kan n gbé igbesi-aye Rẹ ninu rẹ.

44 Oo, ṣe o ni imọlara Ẹmi ti a ti bùkún naa? Iye naa, “Ko ki n ṣe emi ni mo n gbe igbesi-aye naa,” gẹgẹ bi Paulu ti wi, “ṣugbọn Kristi ni o n gbe ninu mi.” O n jade funrara rẹ.

“O dara, mo sọ fun ọ, Arakunrin Branham. A jẹ Kristẹni nibiyi. A ṣe iranlọwọ fun awọn eniyan wọnyi. A n ṣe iranlọwọ fun awọn eniyan.” Akiika, ki oju ki o ti ọ! Eleyi ko ki n ṣe ẹsin Kristẹni. Ẹsin Kristẹni jẹ ohun ti o kan ṣe látinúwá o yẹ ... A gbọdọ ṣe e. O kan gbagbe nipa rẹ, nipa gbogbo .... O si ṣe e.

Kristi kan jọwọ gbogbo aye Rẹ patapata fún Ọlọrun. O fi ara Rẹ silẹ gẹgẹ bi ojiṣẹ-ilu fun awọn eniyan. O fi Ẹmi Rẹ lelẹ lọ́fẹ. Ko nilo lati ṣe e. Kọ se e pẹlu ìkùnsínú. Ko wipe “Bayi, ẹ̀yin arakunrin, o yẹ ki ẹ ni ìrònú pupọ nipa mi nitoripe mo wá lati wá kú fun yin.” Ko sọ ọrọ kankan nipa rẹ̀. O kú ni ọnakọna! Nitoripe Ọlọrun wa ninu Rẹ. O jẹ Ọlọrun ti o wá ninu yin! O jẹ Ọlọrun ti O wà ninu mi! Eleyi jẹ ki a maa wo awọn ẹlomiran.

45 Aguntan ni apa kan.

Ọkan ninu wọn yoo sọ wipe, “O dara, Oluwa, mo ṣe eyi, ati, Oluwa, mo ṣe tọun.”

O wipe, “Ẹ kuro lọdọ mi, ẹyin oniṣẹ ẹ̀ṣẹ̀. Emi kò mọ̀ yin rí paapa.”

Ti ijọ ba le wa si awọn otitọ ti o jẹ ipilẹ, kò ki n ṣe ohun ti o làkàkà lati ṣe, tabi ohun ti o pinlẹ rẹ ninu rẹ lati sẹ; o jẹ ohun ti a bi pẹlu rẹ.

46 Ẹ dariji mi, ẹyin ọrẹ mi ti ẹ jẹ ara ijọ Pẹntikọsti. Emi naa jẹ ara ijọ Pẹntikọsti pẹlu, ṣugbọn awọn ọrẹ mi ti o wa ni Pẹntikọsiti ti de ibi ojú-ami nibiti o jẹ wipe ọpọlọpọ orin ti a yara kọ gbọdọ wa, awọn onilu-ode-oni gbọdọ wa, tabi ki a patẹwọ, tabi awọn ṣẹkẹrẹ, lati le mu ariwo kan jade. Eleyi kàn jẹ ìṣọ̀jìgì ara lásán. Wọn maa n kọrin ki wọn to lọ si oju ogun lati le jẹ ki awọn eniyan wà ninu ẹmi ogun. Mo gbagbọ ninu orin. Mo gbagbọ ninu ki a patẹwọ, ṣugbọn .... mo gbagbọ ninu awọn nkan wọnyi. Eleyi jẹ otitọ. O yẹ ki a ni eléyi, ṣugbọn ẹ fi ohun nla ti o ṣe pataki silẹ laiṣe. Igbesi-aye irubọ-ti-ara-ẹni, eyiti Ọlọrun n gbe ninu yin, ti o si n ṣe ohun ti o tọ́ lái-fi-ipá-ṣe nitoripe o jẹ ohun ti o tọ́ - o si n tẹsiwaju, ko si ro ohunkohun nipa rẹ̀, o kan n gbé igbesi-aye yi ni. Lẹhin naa ṣe akiyesi. Ṣe ẹ ri ohun ti o n ṣẹlẹ, iwọ kàn .... o ko nílò .... o wà ni opopo naa. Ohun ti Kalfari jẹ si ọ nìyí - ni opopo naa - a ṣi ọjọ naa sílẹ̀ fun ọ.

47 Bayi ranti, o ko le jẹ ilaji ewurẹ ati ilaji aguntan. Wọn ko le darapọ. Bayi, ọpọlọpọ awọn eniyan wà ti wọn sọ wipe, “Bẹẹni, ṣe o mọ ohun ti o ṣẹlẹ? A ni ẹgbẹ ti a fi ọgbọn eniyan gbe kalẹ kan. A n ran awọn alaini lọwọ. A n ṣe eleyi,” Gbogbo rẹ dara, ṣugbọn ẹ n pariwo ara yin fun araye gbọ́ ni. Maṣe ṣe eleyi. Ṣe ọrẹ rẹ ni ikọ̀kọ̀, Jesu sọ wipe. Ohun yi a maa ṣẹlẹ funrararẹ lati inu rẹ wá.

Ko ki n ṣe ki a lọ ki a si lọ bu omi mimu nikan. Ongbẹ n gbẹ ọ́. Ti ongbẹ ba n gbẹ ọkunrin ti o wà ni ẹgbẹ́ ọ̀dọ̀ rẹ, iwọ yoo ronu nipa rẹ̀, pẹ̀lú. Aìni arakunrin ti o wà ni ẹ̀gbẹ́ ọdọ rẹ, iwọ yoo ronu nipa rẹ gẹgẹ bi iwọ yoo ṣe ronu nipa àini rẹ, iwọ ko si ni pariwo nipa rẹ, iwọ yoo kan maa gbè igbesi-aye rẹ lọ.

48 Bayi iwọ ko le e jẹ ilaji aguntan ati ilaji ewúrẹ́. Nitorina ti o ba sọ wipe, “O dara, ijọ wa ti ni ẹgbẹ-ti-a-fi-ọgbọ́n eniyan gbé kalẹ kan. A maa n fun awọn alaini. A ṣe tọ̀ún, a ṣe èyí, a sị se ohun míràn.” Ti o bá ni eleyi laisi èyí - igbesi-aye Kristi ninu rẹ dajudaju o kàn n ṣe e lásán ni.

Paulu sọ wipe ninu iwe Korinti kinni ori kẹtala, “Bi mo si fi gbogbo ohun ini mi bọ́ talaka, bi mo si fi ara mi funni lati sun, gẹgẹ bi ìrúbọ, ko li èrè kan fún mi.” Bayi eleyi nira, ṣugbọn otitọ ni. O ni lati wa si otitọ yi. Loye ohun ti Kalfari ṣe fun ọ.

49 A maa n wo o, a si sọ wipe, “oo, bẹni, eleyi dara.” Òhun kọ́ ni èyì. Ti ọmọ Ọlọrun ba ni lati lọ si Kalfari fun kíkàn mọ agbelebu, gbogbo ọmọ ti o ba wá ni lati lọ si Kalfari! O gbọdọ ni Kalfari kan pẹlu. O gbọdọ ni ọjọ

Kalfari naa. Mo gbọdọ ni ọjọ Kalfari naa. Eyi ni o dahun gbogbo ibeere ẹ̀ṣẹ̀. Ko ki n ṣe pe a bọwọ pẹlu oniwaasu, ko ki n ṣe pe a fi wa sinu ijọ kan, ko ki n ṣe pe a wọle pẹlu iwe atẹ-ranṣe, ko ki n ṣe pe a wọle nipasẹ fifi ẹnu jẹ́wọ́ ṣugbọn, a wọle pẹlu ìbí kan.

Ko fi ìwé-atẹranṣẹ sita, kò fi fifi ẹnu-jẹ́wọ́ síta, O fun ni ni ìbí kan. Bayi ni a ṣe n wọlé. Lẹhin naa, lati inu eyi, a o maa gbe igbesi-aye Kristẹni lati inú wá.

50 Bayi ọrọ miran. Ilaji ewurẹ, ilaji aguntan: Wọn ko ni irú nkan bayi. Iwọ ko le jẹ̀ ilaji ewurẹ ati ilaji aguntan, o ṣe e ṣe ki iwọ jẹ ewurẹ tabi ki iwọ jẹ aguntan. Bayi ti iwọ ba kan n ṣe awọn ohun ti o dara, ti o si ro pe iwọ yo wọle nipasẹ eyi, lẹhin naa ko nilo ki a ni ọjọ ti Kalfari naa. Ofin ti pese eleyi. Òfin ti pese eleyi. Ṣugbọn gbigba ọjọ naa ni Kalfari ni yoo mu eleyi wọle - pe a ko ni kan jẹ́ ọmọ ijọ lásán, ṣugbọn a o jẹ awọn ọmọkunrin ati ọmọbinrin Ọlọrun.

Ohun ti ọjọ naa ni Kalfari jẹ niyi. Ohun ti o jẹ si ọ niyi, pe ki o le ṣe e, ki o si tẹle, ki o si hùwà bi i Jesu.

Bayi odò ko ki n sàn lọ si òkè ki o si tun sàn si isalẹ ni ìgbà kannaa. Odo maa n san ni ọ̀nà kan ṣoṣo ni, Ẹmi Ọlọrun si maa n rin ni ọ̀nà kan. Ko ki n mu awọn ohun miran papọ pẹlu ara rẹ̀. O maa n rin ni ọna kannaa.

51 Wo Jesu, ni ipari. Jesu sọ wipe, “Iṣe ti mo ṣe ni ẹyin naa yoo ṣe pẹlu; eyiti o ju eleyi lọ, ni ẹyin yoo ṣe, nitori mo n lọ sọdọ Baba Mi.” Emi ko sọ eleyi ni ọpọlọpọ fun ijọ ti o wà nibiyi nikan, ṣe oye eyi ye yin, ṣugbọn a gba awọn iwaasu yi silẹ. Ẹgbẹrun lọ́na ẹgbẹgbẹrun ni o n gbọ wọn kaakiri gbogbo agbaye. Emi yoo dahun ibeere fun alatako naa nisisiyi. A ti maa n sọ fun mi ni gbogbo igba, wọn wipe, “O dara, ṣe o gba Bibeli gbọ,” Jesu sọ wipe “Iṣẹ wọnyi, ti Emi n ṣe li ẹyin naa yoo ṣe pẹlu; iṣẹ ti o tobi ju wọnyi lọ ni ẹyin yoo sị se, nitoriti emi nlọ sọdọ Baba.”

52 Bawo ni o tị se le buru tó, ọgbẹni? Bawo ni iwọ yoo tị se jìnà tò kuro ni ibi ìmọ̀-ẹ̀mi-yàtọ̀ pẹlu ìmọ̀ ọgbọ́n-ori rẹ ti o ni ni ile-iwe ẹ̀kọ́ ijinlẹ Bibeli, pẹlu ohun gbogbo ti o tumọ nipasẹ ogbọn ori rẹ?

Ẹyin ọ̀rẹ́ mi olore-ọfẹ ti o si ti sọnù, ṣe ẹyin kò loye wipe a ṣe itumọ Bibeli nipasẹ ẹmi? Jesu dupẹ lọwọ Baba pe O fi pamọ́ kuro lọdọ awọn ti o ni ímọ̀-ẹ̀kọ́ ati awọn alagbara, ati awọn ọlọgbọn, ati awọn ti o ni oye, o si fi han fun awọn ọmọde iru awọn ti yoo wá si Kalfari.

53 Bayi ṣe akiyesi. Jesu sọ wipe (ṣe akiyesi bi o ti ṣe sọ ọ), “Iru iṣẹ ti mo n ṣe ....” Oun naa n ṣe irú rẹ bayi. “Iṣẹ ti mo n ṣe lọ́wọ́ bayi [wiwo alaisan san, jiji òkú dide, lila ojú afọju], iru awọn iṣẹ wọnyi ni ẹyin naa yoo ṣe pẹlu. Ẹyin yoo ṣe awọn nkan wọnyi, ti ẹ ba gbagbọ ninu Mi. Ẹyin yoo ṣe awọn iṣẹ wọnyi; ati eyi ti o tobi ju eyi lọ ni ẹyin naa yoo ṣe, nitori Emi n lọ sọdọ Baba Mi. fun ìgbà díẹ̀, ayé kò ni ri Mi mọ; sibẹ ẹyin yoo ri Mi. Emi yoo wà pẹlu yin, ninu yin pàápàá, titi yoo fi de opin ayé. Emi ko ni fi yin silẹ laini Olùtùnnú. Emi yoo gbadura si Baba Oun yoo ran olutunnu miran si yin, eyi ni Ẹmi Mimọ; eyiti aye ko le gba: sibẹ ẹyin le gba A.”

54 Bayi ṣe akiyesi, iṣẹ ti o tobi ju eyi lọ ni pe ki ijọ ni agbara ko ki n ṣe pe ki o gbadura iwosan fun alaisan nikan, ki o le ẹmi-eṣu pẹlu adura, ṣugbọn ki o fun awọn onigbagbọ ni Ìyè Àinípẹ̀kun. Ẹmi Mimọ sọkalẹ wa, a si fi si ọwọ ijọ, lati fi iye ainipẹkun fun awọn eniyan. Ohun ti Kalfari tumọ si niyi.

O wa si ipo ẹgbin, O mu awọn ọkunrin ati awọn obinrin ti wọn wa ni ipo ẹgbin O si fa wọn sókè sí ipò ti wọn yoo fi di awọn ọkunrin ati awọn ọmọbinrin Ọlọrun lati le wo awọn alaisan sàn, ki wọn si fun wọn ni iye ainipẹkun, nipa fifun awọn onigbagbọ ti o gbọ́ràn ni Ẹmi Mimọ. Awọn ọkunrin ti wọn jẹ alaigbagbọ nigba kan ri ti wọn si di onigbagbọ, ti wọn si fi Iye ainipẹkun ti ẹ̀mí fun ni.

55 Bawo ni o tị se tobi to .... Lati sọ fun obinrin alaisan ti o dùbúlẹ̀ sibiyi, “Emi le e gbadura igbagbọ,” oun yoo si gba iwosan, ohun nla niyi. Ohun ti o n ṣe nigba naa nìyí, ṣugbọn o sọ wipe, “iṣẹ ti o tobi ju eyi lọ ni ẹyin yoo ṣe. Emi yoo fun yin ni agbara, ko ki n ṣe pe ki o gbe e dide fun ìgbà diẹ nikan, ṣugbọn ki o fun un ni Iye ainipẹkun - eyiti yoo wà titi laelae.”

Ẹyin òtòṣi, afọju, àre eniyan, bawo ni ẹyin ko ṣe ri eyi? Ṣe ẹyin ko ri ohun ti o tobi ju ti a sọ yi? Ohun ti o tobi ju ti o le ṣẹlẹ, ni wipe ki a fi ìyè ainipẹkun fún awọn eniyan.

56 Kini Iye ainipẹkun? Igbesi-aye ti Oun funraraRẹ gbé. Iye ti o wa ninu Rẹ; fi eleyi sinu ẹlomiran. Ṣe eniyan le ṣe eleyi? Ọmọ Ọlọrun le ṣe e. Jesu sọ wipe, “Ẹṣẹ ẹnikẹni tị eyin ba fi ji, a fi ji wọn; ẹ̀ṣẹ̀ ẹnikẹni ti ẹyin ba da duro, a da wọn duro.” Bayi, ibiyi ni Ijọ Aguda ati ọpọlọpọ awọn iyoku ti ṣe asiṣe nla. Wọn jade lọ wọn si sọ wipe, “Mo dari ẹ̀ṣẹ̀ rẹ ji ọ.” Ohun kọ niyi.

Bawo ni a ṣe n dari ẹ̀ṣẹ̀ ji ninu Bibeli? Peteru dahun si ibere naa ni ọjọ Pẹntikọsti. Wọn so wipe, “Kini ki awa ki o ṣe ki awa ba le gbagbọ? Bawo ni awa yoo ṣe ni, ohun yi tị eyin naa ni?”

O fi ipilẹ bi yoo ti ṣe ri lélẹ. O sọ fun wọn ohun ti wọn yoo ṣe. O wipe, “Ẹ ronupiwada olukuluku yin si

Ọlọrun, ki a si baptisi yin ni orukọ Jesu Kristi.” Nitori kini? “Nitori idariji ẹ̀ṣẹ̀ yin. Iṣẹ ti o tobi julọ niyi.

57 Ẹyin oniwaasu melo ni owurọ yi, melo ninu yin ni o n gbọ ọrọ mi ninu ohùn ti a gba silẹ, ti o ṣetan ni owurọ yi lati lọ si kalfari? Lati wo ohun ti Ọlọrun ṣe nibẹ fun ọ, ki o si kọ ẹkọ adamọ ti ijọ ẹlẹkọ adamọ rẹ silẹ, ki o si waasu ihinrere naa? Hallelujah! O wa lọwọ rẹ bayi! Kini iwọ yoo ṣe pẹlu rẹ? Kini idi? “Ironupiwada ati idariji ẹ̀ṣẹ̀ rẹ ji ni a gbọdọ waasu ni orukọ rẹ fun gbogbo agbaye, bẹrẹ lati Jerusalẹmu. Hallelujah!

Kini Kalfari tumọ si fun ọ? Kini ọjọ naa ṣe fun ọ? Ṣe o mu ọ lọ si ọdọ awọn ẹlẹkọ-ijinlẹ Bibeli kan? Ṣe o sọ ọ di alákatakítí? Tabi ṣe o sọ ọ di Kristẹni, ti o jọwọ gbogbo aye rẹ? Hallelujah! A dari ẹ̀ṣẹ̀ rẹ ji. Iṣẹ ti o tobi ju eyi lọ ni ẹyin yoo ṣe. Ṣe ẹ ri ibiti “ẹyin” naa wà bayi, ṣe ẹ ri i? “Iṣẹ ti o tobi ju eyi lọ” - ki a dari ẹ̀ṣẹ̀ ji ni orukọ Jesu Kristi. Ṣugbọn nipasẹ ẹkọ adamọ, ijọ ẹlẹkọ adamọ, ati bẹẹbẹẹ lọ ti dè ọ mọ́lẹ̀ si ibikan o si tun sin aye.

58 Sọ ọkunrin kan fun mi, sọ obinrin kan fun mi ti yoo wá si Kalfari, ti yoo gbiyanju lati jẹ ẹni nla kan nitoripe ẹnikan sọ ohunkan. Sọ ibiti o ti le wo oju Kalfari, ninu itana-iná rẹ taara, ọjọ naa ni Kalfari ....

Bawo ni iwọ yoo ṣe ni ọjọ rẹ ni Kalfari ki o si tun jẹ́ alákatakítí? Bawo ni iwọ yoo ṣe di òpè fun awọn ẹgbẹ́ ti a fi ọgbọn eniyan gbe kalẹ ki wọn si maa waasu ẹkọ-kẹkọ ti a fi ọgbọn eniyan gbé kalẹ? Kilode ti ko fi jẹ ki o jẹ ẹni irẹlẹ si Ọrọ Ọlọrun? Ti o ba jẹ wipe iwọ dé ibẹ̀, iwọ yoo jade wá pẹlu ìrẹ̀lẹ̀. Bawo ni iwọ yoo ṣe nifẹ lati jẹ ẹni nla kan ninu ẹgbẹ ti a fi ọgbọn eniyan gbe kalẹ̀ pẹlu ìyẹ̀ ni ori fila rẹ; nigbati Jesu Kristi ọmọ Ọlọrun rẹ ara Rẹ silẹ sinu ẹran-ara ti a ṣa lọ́gbẹ́, si oju ti a tutọ́ si, titi O fi di itiju ati ẹni-yẹyẹ nigbati a bọ Ọ si ìhòhò ti a si kàn-An mọ àgbelèbú niwaju gbogbo àgbáyé, ti O kẹgàn ìtìju? Bawo ni iwọ yoo ṣe lọ si Kalfari ki o si wá pẹlu ohun ti o yàtọ̀ si ẹni ti Oun jẹ? O jẹ itiju, o jẹ ohun yẹ̀yẹ́.

'Oo' iwọ yoo sọ wipe, “wọn yoo le mi jáde” jẹ ki wọn o le ọ jade. Ni ọjọ rẹ ni Kalfari. Ọlọrun yoo rin pẹlu rẹ. Ẹ jẹ ki emi tun eyi sọ. Ni ọjọ rẹ ni Kalfari, Ọlọrun yoo rin pẹlu rẹ. Ẹ jẹ ki a gbadura.

59 Oluwa, Ọlọrun o, mu gbogbo wa patapata lọ si Kalfari nisisiyi. Jẹ ki a kuro ninu ọgbọn inu wa, Oluwa - ibẹru eniyan, ibẹru pe kini ẹlomiran yoo sọ. Kini idi, gbogbo agbaye ni wọn fi I ṣe ẹlẹya, wọn fi ṣe yẹ̀yẹ́, ṣugbọn O ṣe ìgbọràn si ikú. O ṣe igbọran si itiju. O ṣe igbọran labẹ ijọba àpapọ̀, a si loye pe nigbati Satani kọlu ayé yi, o di oludari ati alaṣẹ ninu aye yi. O jẹ́wọ́ ohun kannaa niwaju Oluwa wa ti o si sọ wipe, “Gbogbo awọn ijọba aye yi jẹ temi. Emi yoo ṣe ohun ti mo fẹ pẹlu wọn.” A si loye èyí lati ọjọ naa lọ titi o fi de aye yi, labẹ ègún eyiti a n dari rẹ lati ọwọ ẹniti o fa ègún yi. Ṣugbọn, Ọlọrun, Ọlọrun o, a n sin ijọba ti ko nị ègún!

Ọlọrun Baba, ohun iyanu ni o jẹ pe Iwọ tị se awọn ohun nla ninu aworan aye loni yi, ti O si jẹ ki awọn aworan nla bi i awọn ofin mẹwa, ati bẹẹbẹẹ lọ, jade wa: ki awọn ọkunrin ati awọn obinrin ba le ri, ti wọn ko ki n lọ ile-ijọsin, ṣugbọn ti o jẹ ki wọn ri ohun ti o jẹ́. Ọna Ọlọrun jẹ́ ọna ti gbogbo ayé maa n kọ̀, nitoripe o dabi ẹnipe a lọ si ilu Russia labẹ eto iṣejọba ti a n pe ni Kọmunisimu (gbogbo dukia jẹ ti gbogbo ìlú). A wa ninu aye yi, ṣugbọn a ko ki n ṣe ti aye yi. A ti lọ si Kalfari. A ti kan ara wa mọ agbelebu fun ijoba ti Ọlọrun, lati jẹ ọkan lara Rẹ. Ohunkohun to wù ki ayé sọ, a mu ìdúró wa pẹlu awọn diẹ ti a kẹ́gàn. A ti lọ si ajinde.

A si gbagbọ pe eleyi ti sunmọ tosi, Oluwa, si igbàti a o ji wa dide si ijọba ti yoo gbàkóso aye yi, gẹgẹ bi Daniẹli tị se ri i niwaju. O si fọ́ gbogbo aye si ìyàngbò kekere, afẹfẹ si fẹ gbogbo rẹ kuro lori pápá ti a ti n fẹ ọkà ni igba oru. Ṣugbọn awọn òkè, awọn okuta, wọn dagba wọn si di òkè nla ti o bo ayé. Okuta yoo wá. Ọlọrun o, a fẹ ni ipin ninu rẹ! Jẹ ki a sẹ ara wa, ki a gbe agbelebu wa lojojumọ, ki a gbé igbesi-aye wa fun Kristi, ki a gbe igbesi aye wa fun ẹlomiran. Ṣe eyi Oluwa!

60 Ti ẹnikan ba wa nibiyi ni owurọ yi ti ko ba mọ Ọ gẹgẹ bi Olugbala, ti o si fẹ ki a ranti oun ninu adura ipari, ti o si fẹ jẹ ki eleyi jẹ ọjọ Kalfari rẹ, njẹ iwọ yoo gbé ọwọ rẹ sókè ki o si sọ wipe, “Gbadura fun mi, Arakunrin Branham. Mo fẹ Mọ Ọ gẹgẹ bi Olugbala Mi.” Ki Ọlọrun ko bukun fun ọ, arakunrin kekere. Ẹlomiran tun wa bi? Ki Ọlọrun ko bukun fun ọ, arakunrin mi lẹyin lọhun. Ṣe ẹlomiran tún wa ti yoo sọ wipe, “Emi fẹ mọ Ọ, mo fẹ ki eleyi jẹ ọjọ naa ni Kalfari fun mi. Mo n ṣe aisan o si rẹ̀ mi. Kini iwulo pe mo n ṣe alarinkiri pẹlu ohun pataki naa ti a fi bi mi saye pe ki emi wa ṣe emi n ṣere pẹlu rẹ? A bi mi, a bi mi pe ki emi jẹ ọmọ Ọlọrun, ati nibiyi emi n di awọn ohun aye mú. Ọlọrun, loni jẹ ki a kàn mi mọ́ agbelebu. Jẹ ki a kàn mi mọ agbelebu loni, emi ati gbogbo ọgbọ́n-ori mi, ki emi ba le gbé pẹlu Kristi ki n si gbe igbesi aye mi fún awọn ẹlomiran. Ohunkohun ti wọn le ṣe si mi, ti wọn ba fi mi ṣe ẹlẹya, ti wọn ba pọ́n mi loju, ti wọn si sọ oriṣiriṣi ohun buburu si mi ati oriṣiriṣi nkan, jẹ ki emi tẹsiwaju pẹlu irẹ̀lẹ̀, ki n si ni iwa tutu bi i ọdọ-aguntan, gẹgẹ bi Oun ti ṣe. Ni ọjọ kan O ti ṣeleri pe oun yoo tun gbe mi dide ni ọjọ ikẹyin. Emi n fojusọna fun ọjọ naa.”

Ṣe awọn ọwọ yoo tun lọ soke si bi? Ki Ọlọrun ko bukun fun ọ ni ẹyin lọhun, ati iwọ. O dara, awọn ọwọ si. Ki Ọlọrun ko bukun fun ọ. Ki Ọlọrun ko bukun fun ọ. Ki o tun wa si ṣaaju ki a to gbadura.

61 Baba wa ọrun, nigbati Peteru waasu ni ọjọ Pentikọsti a sọ wipe, “A si fi kun ijọ iye awọn ti o gbagbọ.” Wọn gbagbọ ni tootọ pẹlu gbogbo ọkan wọn. Awọn eniyan wọnyi ti wọn ṣẹṣẹ gbé ọwọ́ wọn sóke, mo gbagbọ pe wọn ti gbagbọ pẹlu gbogbo ọkan wọn. Ti wọn ba tị se eleyi, adágún omi wà ti o n duro dè wọn nibiyi. Ti

wọn ba fẹ ki a dari ẹ̀ṣẹ̀ wọn ji ẹnikan wà nibiyi ti o le ṣe iribọmi fún wọn ni orukọ naa, ati orukọ kan ṣoṣo ti o wa ni abẹ́ ọrun ti a fifun eniyan, ti a le fi gba wa là. Nitori gẹgẹ bi mo ti ṣe ka ayọka Iwe-Mimọ ni iṣẹju diẹ sẹyin, pe "ironupiwada ati imukuro ẹ̀ṣẹ̀ ni a gbọdọ waasu ni orukọ Rẹ fun gbogbo àgbáyé, bẹrẹ lati Jerusalemu." Ati ni Jerusalemu nigbati a waasu ironupiwada ati imukuro ẹ̀ṣẹ̀, awọn aposteli sọ fun wọn nipa Iwe Mimọ wọn si sọ wipe wọn gbọdọ kọkọ ronupiwada, ati lẹhinaa ki a ṣe iribọmi fun wọn ni orukọ Jesu Kristi. Ojuṣe oniwaasu niyi lati ṣe. Ki wọn ronupiwada, ki o sị se iribọmi fun wọn fun imukuro ẹ̀ṣẹ̀ wọn. "Ẹṣẹ ẹniti ẹ yin ba fi ji, ohun naa ni a o fi ji wọ́n. Ẹṣẹ ẹnikẹni ti ẹyin ba si da duro, ohun naa ni a da wọn duro."

62 Baba, bawo ni aye yoo ṣe kuro ninu irú ìbínù gbígbóna bi eleyi ti o ẁa ninu rẹ yi? Kilode ti wọn ko fi gba ihinrere ti o rọrún? Ti wọn si tun mu ohun miran wọle dipo rẹ, orukọ èké, iribọmi èké, iribọmi Ẹmi Mimọ eke, bibọ ọwọ pẹlu awọn oniwaasu, lilo apele Baba, Ọmọ ati Ẹmi-Mimọ eyiti ko si ninu Iwe Mimọ rára - akọsilẹ sinu iwe ti a ṣe lati ọwọ awọn ọkunrin ara Romu; ko ki n ṣe ẹkọ Kristẹni rara ko si ni ibikankan ninu Bibeli. Ìmúkúrò ẹ̀ṣẹ̀ ko le mu ẹ̀ṣẹ̀ kuro nipasẹ àpèlé, ṣugbọn nipasẹ orukọ Jesu Kristi.

Bayi, Baba, a mọ wipe eleyi ko ki n ṣẹlẹ nigba gbogbo. Ọna Rẹ maa n ri bayi ni gbogbo igba. Ṣugbọn jẹ ki awọn ọkunrin ati awọn obinrin ni owurọ yi wa si ọjọ naa, ọjọ naa ni Kalfari; nibiti Jesu, ti O kẹgan ọjọ naa, itiju naa pe a bọ aṣọ lara Rẹ̀, ti a sị sa A lọ́gbẹ́, ti a si tutọ si lara ti a si fi I ṣe ẹlẹya lati ọwọ́ gbogbo àgbáyé, lati ọwọ ijọ, lati ọwọ awọn eniyan awọn ti o yẹ ki wọn nifẹ́ Rẹ .... ati sibẹ ninu gbogbo eyi ko ya ẹnu Rẹ, O si lọ O si kú fún gbogbo awọn eniyan ti wọn fi I n ṣe yẹ̀yẹ́.

63 Ọlọrun, mu wa lọ si Kalfari ni owurọ yi. Ti wọn ba si sọ wipe aṣiwere ni wa, ti wọn ba si sọ wipe a mọ Iwe Mimọ sódi, ohunkohun to wù ti wọn ba fẹ sọ, Ọlọrun, wọn ko le duro niwaju Ọlọrun ki wọn si sọ wipe eleyi kùnà.

Wọn ko le bo ẹ̀ṣẹ̀ wọn pẹlu Bibeli. Bibeli ṣi aṣọ kuro loju ẹ̀ṣẹ̀ wọn, aigbagbọ wọn - lati le lokiki, lati le ṣe gẹgẹ bi i awọn eniyan iyoku. Jẹ ki wọn wa si Kalfari ni òwúrọ̀ yi ki wọn si bẹ̀rẹ̀ ni Jerusalẹmu, "Pe ironupiwada ati imukuro ẹṣẹ ni a gbọdọ waasu ni orukọ Rẹ fun gbogbo awọn orilẹ-èdè, bẹrẹ lati Jerusalẹmu." Jẹ ki wọn gbé igbésẹ̀ àgbelèbu kannaa ki a gé wọn si wẹ́wẹ́, ki a si tutọ si wọn lara, ki a si fi wọn ṣe ẹlẹya, ki a si pe wọn ni oriṣiriṣi orukọ ti a le pe wọn ni ti ọna ẹsin ti o jẹ àbùkù - awọn ti o n pin awọ́n ijọ níyà, oriṣiriṣi ti wọn fẹ lati pe wọn.

Jẹ ki awa, Oluwa, ni owurọ yi, mu ìdúro wa pẹlu awọn diẹ ti o jẹ ti Oluwa ti a kẹ́gàn. Jẹ ki a rin bi awọn aposteli tị se, ti wọn ko yà si ọ̀tún tabi òsì, ki a sin Ọlọrun pẹlu inúre ti ọkàn. Ṣe eleyi, Baba.

Bayi, wo awọn alaisan sàn ati awọn ti a pọ́n loju ti wọn yoo wa si ibi ìlà àdúrà. Jẹ awọn ti wọn gbe ọwọ́ wọn sókè yi ninu ọkàn wọn ronupiwada nisisiyi. Jẹ ki awọn ti wọn ti duro sẹyin fún igba pipẹ lọ si ibi omi ni kíákíá ki a si ṣe imukuro ẹ̀ṣẹ̀ wọn lori orukọ irubọ naa, Jesu Kristi Ọmọ Ọlọrun. Amin.

MESSAGE hub online

www.messagehub.info

Ìwàásù lati ẹnu

William Marrion Branham

"... Ati ni ọjọ́ ohùn angẹli keje ..." Ifihan 10:7